“Ẹ ge awọn tubọmu ki ẹ si da awọn irungbọn si”

Lati ọdọ ọmọ Umar- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- lati ọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: “Ẹ ge awọn tubọmu ki ẹ si da awọn irungbọn si”.
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n pàṣẹ pẹlu mimu kuro lara tubọmu ati pe wọn ko gbọdọ fi i kalẹ bi ko ṣe pe ki wọn ge kuro nibẹ, ki wọn si ge e gan. Ni ti idakeji, o n pàṣẹ pẹlu dida irungbọn si ati fifi i kalẹ ni nnkan ti o maa pọ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3279